# OFIN MẸWAA

## Ẹksodu 20:1-17

## ẸKỌ 61 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitoripe a kó gbogbo ofin já ninu ọ̀rọ kan, ani ninu eyi pe; Iwọ fẹ ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ" (Galatia 5:14).**

### Niwaju Oke ti N Rú Eefin

Wakati ti Ọlọrun yoo ba Israẹli sọrọ ti de. Eefin n rọ́ jade bi ẹfuufu lile lati ori oke nla naa ti n rọkẹkẹ̀ ti o si n mi titi pẹlu ọlanla ifarahàn Ọlọrun. Manamana n kọ laaarin awọsanma dudu, iro ipe si n dun kikankikan lati pe awọn eniyan sunmọ tosi lati gbọ ọrọ Ọga-Ogo.

Ko ti i si igba kan ṣiwaju eyi, tabi lẹyin rẹ ti iru iwaasu bayii ṣẹlẹ nigba ti Ọlọrun funra Rẹ̀ sọkalẹ lati ba agbajọ eniyan sọrọ. Wọn ti ri iṣẹ ọwọ Rẹ̀, ṣugbọn wọn kò ti i ri iru ifarahàn Rẹ̀ bayii rí. Oluwa sọrọ lati ori oke O si pe Mose ati Aarọni lati goke wa. Gbogbo eniyan ni o gbọ́ ohùn Ọlọrun, bi o tilẹ jẹ pe wọn ko ri Ọlọrun funra Rẹ̀.

Ọlọrun bẹrẹ ọrọ Rẹ̀ bayii pe, "Emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o mú ọ jade lati ilẹ Egipti, lati oko-ẹrú jade wá". Israẹli mọ eyi tẹlẹ, ṣugbọn wọn tete yara gbagbe to bẹẹ ti Ọlọrun fi ni lati maa rán wọn leti pe Oun ni Oluwa wọn. Wọn jẹ eniyan Rẹ̀ nitori awọn majẹmu ti O ti ba iran wọn dá lati ọdọ Abrahamu.

Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ gbọran si Oun lẹnu nitori wọn fẹran Rẹ̀; ṣugbọn O tun n fẹ ki wọn mọ bi Oun ti jẹ alagbara to, ki ẹ̀rù ba le ba wọn lati ṣaigbọran si I; nitori bẹẹ ni irọkẹkẹ ati iná ati eefin ṣe ṣẹlẹ.

Awọn ọrọ ti Oluwa sọ ni eti gbogbo eniyan naa ni a n pè ni Ofin Mẹwaa, tabi Ofin (Deuronomi 4:13). Sibẹ, awọn nnkan ti o di mọ Ofin ju Ofin Mẹwaa lọ, gẹgẹ bi a o ti kọ́ ninu ẹkọ yii.

### Kò si Ọlọrun Miiran

"Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi." Eyi ni ofin kin-in-ni ti Ọlọrun fi fun ni, o si ṣe pataki pupọ. Awọn Ọmọ Israẹli n lọ si ilẹ kan nibi ti awọn eniyan ibẹ ti n sin oriṣiriṣi oriṣa ati ọlọrun eke, Oluwa si n kilọ fun wọn pe wọn kò gbọdọ kọ́ aṣa ilẹ naa lọnakọna. O wi fun wọn pe Ọlọrun owu ni Oun I ṣe, Oun kò si fẹ ọlọrun miiran lẹyin Rẹ̀.

Awọn Ọmọ Israẹli ti ri ohun ti o de ba awọn ọlọrun asán ti awọn ará Egipti ati bi kò ti jamọ nnkan kan lati sin wọ́n. Awọn ará Egipti maa n bọ odo Nile, ṣugbọn a sọ ọ di ẹjẹ̀ kò si dara fun lilo fun sá à kan. Wọn lero pe ọkan ninu awọn ọlọrun wọn wá si ayé ni awọ maluu, ṣugbọn nigba ti Ọlọrun rán arun sara awọn ẹran, awọn maluu "mimọ́" paapaa kù. Wọn n bọ ọlọrun oorun, ṣugbọn nigba ti Ọlọrun rán okunkun sori ilẹ naa fun ọjọ mẹta, ọlọrun wọn ko tilẹ le fun wọn ni imọlẹ ninu ile wọn. À bá ro pe o yẹ ki awọn Ọmọ Israẹli le mọ pe isinwin ni iru ẹsin bẹẹ, ṣugbọn ninu ọkàn wọn ni ifẹ wà lati yí pada si nnkan miiran ti wọn ṣe bi o rọrun ju isin otitọ lọ; nitori bẹẹ ni Ọlọrun ṣe kilọ fun wọn pe "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi." Lẹyin gbogbo nnkan yii a oo ri i pe ko pẹ ti a fun wọn ni Ofin ni wọn yá ere wura lati maa sin. Ni tootọ alaimoore eniyan ni wọn i ṣe.

### Ipada Sẹyin Israẹli

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli gbọ́ ti Ọlọrun ba wọn sọrọ lati ori oke wá, wọn sá sẹyin. Ẹrù ba wọn, wọn si sọ fun Mose pe ki oun nikan goke lọ lati ba Ọlọrun sọrọ, nitori o dá wọn loju pe awọn yoo kú bi Oun ba bá wọn sọrọ. I ba ṣe pe wọn wa lailẹṣẹ wọn ki bá ti bẹru Oluwa. Ẹlẹṣẹ maa n bẹru idajọ Ọlọrun, ṣugbọn nigba ti a ba dari ẹṣẹ rẹ ji i oun a maa fẹran Ọlọrun, ẹ̀ru kan ṣoṣo ti o si ni ni pe ki oun ma ṣe mu Ọlọrun binu.

### Imọ Ohun Rere ati Buburu

Ki a to fi Ofin fun ni ni awọn eniyan ti mọ rere yatọ si buburu. Irọ́ ti wọn kọkọ pa ni Ọgbà Edẹni kó Adamu ati Efa sinu wahala nla nitori bẹẹ wọn mọ̀ pe ko tọna lati purọ. Adamu ati Efa si mọ pe Ọlọrun n fẹ ipo kin-in-ni ninu ọkàn wọn. O si n fẹ igbọran wọn; nitori lẹsẹkẹsẹ ti wọn ti ṣaigbọran si I, wọn lọ fi ara wọn pamọ. Kaini mọ pe ipaniyan kò dara nigba ti oun pa Abẹli aburo rẹ ni atetekọṣe, nitori o sá lọ ki o ma ba jiya.

### Aworan ni Ofin Jẹ́

A le sọ nisisiyii pe Ọlọrun n fi aworan lelẹ ni fun awọn eniyan naa; O n fi ofin nipa igbesi-aye lelẹ ni ọna ti wọn le fi oju wọn ri. Boya ẹ̀ṣẹ wọn yoo di pupọ to bẹẹ ti wọn ko fi ni le gbóhùn ẹri ọkàn; nigba naa wọn o ri Ofin ti a kọ sara okuta lati maa rán wọn leti ifẹ Ọlọrun.

Jesu kọ́ ni pe ifẹ ni akoja Ofin. Bi a ba fẹran Ọlọrun bi o ti tọ́ ti a kò si ni ọlọrun miiran lẹyin Rẹ̀, ifẹ yii yoo maa ṣakoso iwa wa. Bi a ba fi gbogbo ọkàn wa fẹran Ọlọrun, a oo fẹran ọmọnikeji wa; bi a ba si fẹran ọmọnikeji wa, a kò ni ja a lole, a kò si ni purọ mọ ọn tabi fun un, bẹẹ ni a kò si ni fẹ ohun ti i ṣe ti rẹ̀. Nigba ti ifẹ yii ba si wà ni ọkàn wa, a kò le korira ẹnikẹni, o si daju pe a kò ni pa ẹnikẹni.

### Igbala nipa Igbagbọ́

Ṣugbọn eniyan kò le pa Ofin mọ́ ninu agbara ti rẹ̀ nigba naa, tabi lonii. Paulu wi pe: "A mọ̀ pe a ko da ẹnikẹni lare nipa iṣẹ ofin, bikoṣe nipa igbagbọ́ ninu Jesu Kristi" (Galatia 2:16). Igbagbọ́ ninu Kristi, ni akoko Mose paapaa, ni o gba awọn eniyan là ti o si fun wọn ni agbara lati gbọran si Ofin. Nigba ti ọkunrin kin-in-ni dẹṣẹ, a ṣe ileri Messia kan, Ẹni ti yoo rà á pada (Gẹnẹsisi 3:15). Abrahamu pẹlu si gba ileri Olugbala: "Ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye" (Gẹnẹsisi 12:3). A gba awọn Ọmọ Israẹli là nipa fifi igbagbọ́ wo ọjọ iwaju fun Ẹjẹ Jesu ti a ta silẹ.

**Igba ti O "Sàn Jù" Bẹẹ lọ**

Awọn ẹlomiran gbagbọ́ pe awọn Ọmọ Israẹli nikan ni a fi Ofin fún, ṣugbọn Ọlọrun fi fun wọn ki wọn ba le fi fun "gbogbo idile aiye" (Gẹnẹsisi 12:3) ni. Nitori naa "Awọn li a fi ọ̀rọ Ọlọrun le lọwọ" (Romu 3:2). A sọ pe ki a to fun awọn eniyan naa ni Ofin Mẹwaa ni wọn ti mọ ohun ti o dara yatọ si buburu, koko ohun ti o si wa ninu rẹ ko yi pada lẹyin ti Kristi ti "mu ofin ṣẹ" tán. Ninu Iwe Heberu a ri Paulu bi o ti n fi ọrọ pupọ ṣe akawe laaarin igba aye Ofin ati igba oore-ọfẹ, lẹyin ti Jesu de. Ohun ti wọn tẹnu mọ ninu Iwe naa ni "dara jù." A le fi igba Ofin wé oṣupa ti n fun ni ni imọlẹ ni oru, ṣugbọn ti kò wulo nigba ti ilẹ ba mọ ti oorun si yọ. Bi oṣupa ba wa ni awọsanma bẹẹ ni owurọ, a le ri i bi a ba tẹju mọ ọn; ṣugbọn imọlẹ oṣupa kò ni agbara ninu itanṣan imọlẹ oorun eyi ti o mọlẹ ju lọ, ti o si "dara jù" lọ.

Bakan naa ni o ri nigba ti a ba tọ Kristi wá ti a si jẹ ki Ẹjẹ Rẹ̀ wẹ ẹ̀ṣẹ wa nù, oore-ọfẹ ti O n fun ni lati sin In pọ to bẹẹ ti a ko tun ni i ṣe aniyan nipa pipa Ofin mọ́. A fun ni ni Ofin ki ẹlẹṣẹ ba le mọ rere yatọ si buburu; ṣugbọn Onigbagbọ́ ti o ni Kristi ninu igbesi-aye rẹ, ni Ẹmi ninu rẹ ti o le pa ọrọ Ofin mọ ati ju bẹẹ lọ (1 Timoteu 1:9).

Awọn akọwe ati awọn Farisi nigba aye Jesu fi ṣe ohun danindanin lati pa afarawe Ofin mọ, ṣugbọn Jesu sọ fun awọn ti o fẹ jẹ ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Bikoṣepe ododo nyin ba kọja ododo awọn akọwe ati ti awọn Farisi, ẹnyin ki yio le de ilẹ-ọba ọrun bi o ti wù ki o ri" (Matteu 5:20). Ẹmi ti o n gbe inu Onigbagbọ́ ni Jesu tẹnu mọ. Ofin wi pe, "Iwọ kò gbọdọ pania" nitori bẹẹ awọn Farisi ṣọra ki wọn má pa eniyan; ṣugbọn Jesu wi pe bi ẹni kan ba korira arakunrin rẹ̀; ẹbi rẹ jẹ bakan naa niwaju Ọlọrun bi ẹni pe o lu u pa. Bi eniyan kò ba ti ri igbala oun kò le bọ lọwọ ikorira; ṣugbọn nigba iyipada ọkàn, Jesu maa n mu ẹmi ikorira yii kuro, Oun a si gbin ifẹ Rẹ̀ sibẹ. Ni ọna kan naa Jesu mu awọn Ofin iyoku O si fi hàn pe ète ti o wà lẹyin iwa ti eniyan ba hu buru bakan naa bi ẹni pe wọn ru Ofin ti o wi pe "Iwọ kò gbọdọ ṣe ojukokoro," Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga," ati bẹẹ bẹẹ lọ (Wo Matteu 5).

**Ẹni ti o Yeje**

Onigbagbọ́ maa n fẹ lati mọ inu Ọlọrun, oun a si maa ka gbogbo Bibeli tọkantọkan, ki o ba le maa wu U ninu igbesi-aye rẹ̀. Nigba ti eniyan ba ri igbala, kò bọ́ lọwọ ewu ifasẹyin bi oun kò ba si ka Ọrọ Ọlọrun yoo jẹ ki Satani fa oun pada sinu ẹ̀ṣẹ lai pẹ. A ni lati maa kọ́ Iwe Mimọ́ (Ọrọ Ọlọrun ki a ba le mọ ifẹ Ọlọrun, ki a ba le jẹ aṣiṣẹ ti ko ni lati tiju (2 Timoteu 2:15). "Gbogbo iwe-mimọ́ li o ni imisi Ọlọrun ti o si ni ère fun ẹkọ́, fun iba-ni-wi, fun itọ́ni, fun ikọ́ni ti o wà ninu ododo: ki enia Ọlọrun ki o le pé, ti a ti mura silẹ patapata fun iṣẹ rere gbogbo" (2 Timoteu 3:16, 17).

**Awọn Irubọ Majẹmu Laelae**

Jesu wi pe; "Ẹ máṣe rò pe, emi wá lati pa ofin tabi awọn wolĩ run: emi kò wá lati parun, bikoṣe lati muṣẹ" (Matteu 5:17). Gbogbo ẹjẹ ẹbọ ti a ti ta silẹ, gbogbo isin tẹmpili ti awọn Ọmọ Israẹli ti ṣe gẹgẹ bi Ofin, ni o n tọka lọna kan tabi lọna miiran si akoko ti Jesu yoo wá lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun igbala wa. Gbogbo nnkan wọnyii jẹ apẹẹrẹ ohun ti ẹmi, awọn nnkan ti Ọrun ti n bọ̀ wá.

Nigba ti Jesu kú ni Kalfari O ti mu gbogbo ofin irubọ ṣẹ, kò si ṣanfaani mọ fun awọn Ju lati maa pa wọn mọ́. A ti kà pe Jesu ni Ọdọ-agutan Irekọja wa (Ẹkọ 56), ko si ṣanfaani mọ́ fun awọn Ju lati pa ọdọ-agutan jẹ mọ fun Ajọ Irekọja lẹyin ti Oun ti ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ. Awọn ti o n ṣe Ajọ Irekọja lonii n fi akoko wọn ṣofo ni, nitori Ọlọrun kò ni inu didun pẹlu eto wọn, eyi ti kò tilẹ ṣe deedee pẹlu awọn aṣẹ inu Majẹmu Laelae.

A o maa kẹkọọ si i niwaju nipa ijọsin ti agọ ati ẹbọ pẹlu ohun miiran ti o tọka si Jesu, gbogbo nnkan wọnyii ni Oun si mu ṣẹ ni igbesi- ayé Rẹ̀, iku ati igoke re Ọrun Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni a ti fi Ofin fun ni? Nitori ki ni?
2. Taa ni gbọ́ ohùn Ọlọrun?
3. Ki ni ṣe ti awọn eniyan naa sá sẹyin?
4. Ka Ofin Mẹwaa.
5. Bawo ni igba titun ṣe tobi ju igba laelae lọ?
6. Bawo ni a ṣe n gbà wá là?